# ẸBẸ MOSE FUN IFARAHAN ỌLỌRUN

## Ẹksodu 33:1-23

## ẸKỌ 68 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Oju mi yio ma bá ọ lọ, emi o si fun ọ ni isimi" (Ẹksodu 33:14).**

**I Kíkọ̀ Ọlọrun lati bá Awọn Ọmọ Israẹli lọ si Kenaani**

1. Ọlọrun dari Mose lati mu awọn Ọmọ Israẹli lọ si Kenaani ki O ba le mu ileri ti O ṣe fun awọn baba wọn ṣẹ, Ẹksodu 33:1; Gẹnẹsisi 12:1; 15:18-21; 17:8; 28:13, 14; Orin Dafidi 105:42
2. Ọlọrun ṣeleri lati rán angẹli kan ṣiwaju awọn Ọmọ Israẹli, niwọn bi Oun kò ti ni le bá wọn lọ nitori ẹ̀ṣẹ wọn, Ẹksodu 33:2, 3; Jọṣua 7:12; Orin Dafidi 66:18; Isaiah 59:2
3. Ọkàn awọn Ọmọ Israẹli gbọgbẹ nitori ọ̀rọ wuwo yii, Ẹksodu 33:4-6; Orin Dafidi 34:18; 51:17; Isaiah 66:2
4. Mose gbé Agọ Ajọ lọ si ẹyin ibudo, awọn eniyan si lọ sibẹ (eyi ki i ṣe Agọ ti awọn alufaa n ṣe iṣẹ isin ninu rẹ̀ ti a kọ́ nigbooṣe), Ẹksodu 33:7, 8; Orin Dafidi 34:4; Heberu 10:25

**II Ẹbẹ Mose fun Awọn Ọmọ Israẹli**

5. Ifarahàn Ọlọrun ninu Agọ Ajọ fi hàn pe Ọlọrun ni o n dari Mose, Ẹksodu 33:9-11; Heberu 13:7
6. Jọṣua, iranṣẹ Mose fi iduro ṣinṣin rẹ̀ ninu Ọlọrun ati ijolootọ rẹ̀ si Mose hàn nipa ailọ kuro ninu Agọ Ajọ, Ẹksodu 33:11; 17:9, 10, 13; 24:13; 32:17
7. Mose fi igboya, ti o ti inu aimọ-ti-ara-rẹ-nikan ati ayé ti o kún fun Ẹmi Ọlọrun tọ Ọlọrun lọ lati bẹbẹ pe ki oun le tubọ mọ Ọlọrun ati ọna Rẹ̀ ni pipé, Ẹksodu 33:12, 13; Jeremiah 9:23, 24; 31:34; Hosea 6:3; Johannu 7:12
8. Ọlọrun ṣeleri lati fi ibeere Mose fun un, Ẹksodu 33:14; Isaiah 63:9-14; 54:7, 8; Orin dafidi 78:52-55; 2 Peteru 1:3
9. Mose di ileri naa mú niwọn bi o ti jẹ pe o beere fun ogo Ọlọrun, fun ire awọn Ọmọ Israẹli ati fun ẹri si awọn alaiwa-bi-Ọlọrun, Ẹksodu 33:15, 16; Marku 16:17; 1 Awọn Ọba 8:56
10. Ọlọrun fun Mose ni idaniloju siwaju si i fun esi ibeere rẹ̀, Ẹksodu 33:17
11. Mose n fẹ gidigidi lati ni ibarẹ ti o jinlẹ pẹlu Olodumare, o si beere ohun ti o ga ju lọ lọwọ Ọlọrun, Ẹksodu 33:18, 19
12. Ọlọrun fi ibeere Mose fun un niwọn bi o ti le gba a mọ, Ẹksodu 33:20-23; Johannu 1:18

## ALAYE

**Ileri ti Kò le Yẹ̀**

Ni ibẹrẹ orilẹ-ede awọn Heberu, nigba ti a pe Abrahamu jade kuro ni ilẹ Uri, Ọlọrun ṣeleri pe iru ọmọ Abrahamu ni yoo jogun ilẹ Kenaani. A tun ileri yii ṣe fun Isaaki ati Jakọbu lẹyin naa, ṣugbọn kò si ọ̀kan ninu awọn mẹtẹẹta ti o ri imuṣẹ ileri naa. Wọn n gbé inu agọ, wọn si lo pupọ ninu ọjọ ayé wọn ninu irinkiri ilẹ naa. Ṣugbọn Ọlọrun ko gbagbe awọn ileri Rẹ̀; nigba ti awọn Ọmọ Israẹli kigbe nitori ipọnju wọn, Oluwa mu wọn jade kuro ni Egipti lọna iyanu, O si bẹrẹ si tọ́ wọn lọ si Kenaani.

Awọn Ọmọ Israẹli da Ọlọrun, wọn si kuna lati de àyè ti o fẹ mu wọn de, ṣugbọn ileri Ọlọrun fun Abrahamu wà sibẹ. Inu Ọlọrun kò dun si awọn Ọmọ Israẹli nitori ẹ̀ṣẹ wọn. Oun i ba pa wọn run bi ko ba ṣe pe Mose bẹbẹ gidigidi fun wọn. Mose rán Ọlọrun leti pe awọn eniyan ki yoo bu ọla fun orukọ Rẹ̀ bi O ba pa Israẹli run. Bi ko ba jẹ ti adura Mose ni, iru aṣẹ ti o jade leti Ilẹ Ileri – pe kò si ẹni ti yoo wọ ilẹ Kenaani – ni i ba jade si wọn lẹba Oke Sinai.

Ọlọrun yí idajọ naa ti I ba mu wa sori Israẹli kuro; lẹyin ti ẹ̀yà Lefi si ti ya ara wọn sọtọ kuro lara awọn ẹ̀yà ti o kù, Ọlọrun paṣẹ pe ki wọn ṣi kuro ni Oke Sinai ki wọn si bẹrẹ si i rin irin-ajo gigun naa lọ si Kenaani. O ranti ileri ti o ti ṣe fun Abrahamu, Isaaki, ati Jakọbu. O fun awọn Ọmọ Israẹli ni anfaani kan si i lati fi iwa otitọ ati ifẹ wọn hàn si I. Ṣugbọn nitori ẹ̀ṣẹ ti o wà laaarin awọn eniyan naa Ọlọrun kò le gbé laaarin wọn.

**A Gbọdọ ni Iwa-Mimọ́**

Ọlọrun kò le gbe ibi ti a ba gba ẹ̀ṣẹ laye tabi ibi ti a fara mọ ẹ̀ṣẹ. Nigba ti Jesu kú ni Kalfari, O ru gbogbo ẹ̀ṣẹ wa, O si kú ki awa ma ba kú; ẹ̀ṣẹ wa ti Ẹni Mimọ́ yii rù mu ki Ọlọrun yí oju Rẹ̀ kuro lara Ọmọ Rẹ̀ ọ̀wọ́n kan ṣoṣo naa. Ọlọrun kò le boju wo ẹ̀ṣẹ nigba ti Kristi ku, bakan naa ni kò le gbe ibi ti ẹ̀ṣẹ wa ni akoko ti awọn Ọmọ Israẹli. Bẹẹ ni Oun kò le pe ẹni naa ti o gba ẹ̀ṣẹ laya rẹ̀ ni ọmọ ni akoko yii.

Aanu dapọ mọ́ idajọ ninu ipinnu Ọlọrun pe Oun ki yoo wà laaarin awọn Ọmọ Israẹli. Ki yoo jọwọ wọn silẹ patapata fun ọna ti wọn, ṣugbọn O ṣeleri lati rán angẹli kan ti yoo ṣe amọna wọn lọ. Nitori iwa ẹ̀ṣẹ wọn, O fi aanu fà sẹyin, ki Oun ma ba pa wọn run ninu ẹ̀ṣẹ wọn nigba ti wọn ba yi pada kuro lọdọ Rẹ̀ bi wọn ti maa n ṣe tẹlẹ. Nipa

bayii a oo daabo bo wọn kuro lọwọ idajọ ojiji a oo si fun wọn ni afo lati ronupiwada ati lati yi ọkàn pada sọdọ Ọlọrun.

**Agọ-Ajọ**

Nigba ti Ọlọrun kuro laaarin wọn, wọn sọ anfaani ati oju rere nla kan nù: eyi ni ni wiwà ti Ọlọrun wà laaarin wọn gẹgẹ bi Alakoso, Olutọ, Alaabo ati Igbala wọn. Wọn kaanu, wọn si kọ̀ lati wọ ohun ọṣọ sara. Bi o tilẹ ṣe pe wọn jẹ alagidi, ẹlẹṣẹ, ati abọriṣa, wọn kò fẹ ki Ọlọrun fi wọn silẹ; nigba ti Mose si sọ ọrọ Oluwa fun wọn, inu wọn bajẹ gidigidi. Wọn kaanu fun ẹ̀ṣẹ wọn ju ti igbakigba ṣiwaju akoko yii, wọn si bọ́ gbogbo ọṣọ wọn kuro lara. Ọlọrun ri ironupiwada wọn.

Ki a to kọ́ Agọ ti i ṣe ile gidi, apẹẹrẹ eyi ti a fi hàn Mose lori Oke Sinai, awọn Ọmọ Israẹli ti ni ibi kan ti Ọlọrun n pade wọn. Eyi ni a n pè ni Agọ Ajọ, on ni a si ro pe yoo jẹ ibi ti Mose n gbé, tabi ibi pataki ti o maa n fi àbọ̀ si. Nigba ti Ọlọrun sọ ipinnu Rẹ̀ fun Mose, o gbe Agọ yii jade lọ si ẹyin ibudo o si gbe e kalẹ si okeere, lati fi hàn gbangba fun awọn Ọmọ Israẹli pe Ọlọrun ki yoo duro laaarin wọn mọ. Mose tun fi ipinnu rẹ̀ hàn pe ohunkohun ti o wu ki o gba oun, oun n fẹ wa ni ibi ti ifarahan Ọlọrun gbe wa.

Awọn Ọmọ Israẹli bẹrẹ si ronu nipa iduro wọn nipa ti ẹmi nigba ti iyipada yii de, wọn a si duro lẹnu ọna agọ wọn nigba ti Mose ba n lọ sinu Agọ. Bawo ni yoo ti dun mọ wọn to nigba ti wọn ri ọwọ̀n awọsanma ti o sọkalẹ sori Agọ, nitori wọn mọ pe Ọlọrun n ba Mose sọrọ, eyi si n fun wọn ni idaniloju pe Ọlọrun yoo maa tọ́ wọn lọ.

**Jọṣua Oloootọ Ọmọ-ogun**

Ki i ṣe Mose nikan ni o mu iduro fun Ọlọrun. Nigba gbogbo ni o ma n ku awọn eniyan mimọ diẹ sibẹ lọkunrin ati lobinrin ti wọn mu iduro fun igbagbọ́ laaarin ifasẹyin kuro ninu igbagbọ ati igba ti ẹ̀ṣẹ gbilẹ kan. Ọlọrun ki i ṣalai ni awọn “Samuẹli” ti yoo maa gbọ́ ohùn Ọlọrun sibẹ nigba ti awọn “Eli” kò le gbọ́ mọ; “awọn ẹẹdẹgbaarin (7,000)” ti ko ni tẹ eekun wọn ba fun oriṣa bi o tilẹ jẹ pe awọn “Elijah” ko mọ wọn; awọn “Eliṣa” ti n tu omi si ọwọ awọn “Elijah,” “awọn ọmọ Heberu” ti o mu iduro wọn pẹlu awọn “Daniẹli” oloootọ; ati awọn “Jọṣua,” awọn ẹni ti ki yoo kuro ninu Agọ, nigba ti a mu Ẹmi Ọlọrun binu nitori ẹ̀ṣẹ.

Jọṣua yii kan naa ni kò bẹru lati gba ogun jọ ati lati doju kọ ewu nla ninu ogun pẹlu awọn akikanju ọmọ-ogun Amaleki, nigba ti Mose paapaa n gbadura fun iranlọwọ fun awọn ọmọ-ogun Israẹli. Jọṣua yii kan naa ni o gun ori Oke Sinai lọ pẹlu Mose, jinna ju awọn miiran lọ. Ati nihin yii gẹgẹ bi oloootọ iranṣẹ Mose, a ri i ti o n ṣe ojuṣe ti rẹ̀. Ki Oluwa ki o fun wa ni awọn ẹni bi Jọṣua!

**Ẹbẹ Mose fun Ifarahàn Ọlọrun**

Eto ti a fi lelẹ ko tẹ́ Mose lọrun. O mọ iwuwo iṣẹ ti o wà ni ejika rẹ̀. O mọ awọn eniyan wọnyii pe wọn maa n kùn, wọn si maa n kun fun ijaya, wọn maa n yara pada lẹyin Ọlọrun. O mọ̀ pe ninu agbara oun, oun ko le mu awọn eniyan naa de ilẹ Kenaani. Ọlọrun ti ṣeleri lati rán angẹli kan ṣiwaju wọn ṣugbọn eyi ko to fun Mose, bẹẹ ni o si tun woye pe ọna ti Ọlọrun n fẹ gbà ko hàn gbangba si oun to. Bi o ba ṣe pe ni tootọ ni oun jẹ ẹni ti o sun mọ Ọlọrun timọtimọ gẹgẹ bi Ọlọrun ti wi, o yẹ ki Ọlọrun duro ti oun gbọningbọnin ju ti atẹyinwa lọ. Oun kò fẹ mọ nipa ọna eniyan to bẹẹ, bẹẹ ni oun ko fẹ i mọ giga ti ayé yii, o fẹ mọ Ọlọrun si i. O n fẹ mọ gbogbo ohun ti Ọlọrun n fẹ patapata. O n fẹ ni oju rere Ọlọrun si i.

Ọlọrun bọla fun adura Mose o si fun un ni idaniloju bayii pe “Oju mi yio ma bá ọ lọ.” Nitori ẹbẹ ati adura Mose oju Ọlọrun yoo maa bá wọn lọ dipo pe ki angẹli kan maa lọ niwaju wọn lati ṣamọna wọn. Mose rọ̀ mọ́ ileri yii gẹgẹ bi o ti fi hàn ninu idahun rẹ: “Bi oju rẹ kò ba bá wa lọ, máṣe mú wa gòke lati ihin lọ.” Mose ti ri oju rere lọdọ Ọlọrun.

O sàn lati kú ni aginju Sinai ju lati rin irin ọjọ kan ṣoṣo lai ni Ọlọrun laaarin wọn! O sàn lati gbé ilẹ aṣalẹ ju ilẹ ti n ṣàn fun wara ati fun oyin lai si Ọlọrun! Bawo ni a o ṣe mọ̀ wọ́n yatọ laaarin awọn eniyan ayé bi ko ṣe pe Ọlọrun ba n gbé aarin wọn? Bawo ni wọn o ṣe mọ pe awọn n tẹle ifẹ Ọlọrun bi Oun kò ba wa pẹlu wọn? Bawo ni wọn o ṣe mọ̀ ni tootọ pe angẹli Oluwa n ṣiwaju wọn lọ bi Ọlọrun ko ba wà pẹlu wọn nigba gbogbo?

Awọn Onigbagbọ ọjọ oni le kọ́ ẹkọ iyebiye lara Mose, eniyan Ọlọrun, ti o taku ti Ọlọrun ni akoko yii ni igbesi-ayé rẹ̀. Bawo ni a ṣe le mọ pe a yà wá kuro, a si yà wa sọtọ kuro laaarin awọn eniyan ayé bi ko ba ṣe pe Ọlọrun wa pẹlu wa? Bawo ni a ṣe le mọ ifẹ Ọlọrun, bi Ọlọrun ko ba wà pẹlu wa? Bawo ni a ṣe le ni idaniloju pe angẹli Oluwa n lọ ṣaaju wa bi Ọlọrun ko ba wà pẹlu wa? Bawo ni a ṣe le ṣe aṣeyọri ninu isin Ọlọrun bi Oun ko ba wà pẹlu wa? Ifarahàn Ọlọrun, Ẹmi Mimọ́ Rẹ̀, ni o yẹ ki a jijakadi fun ki a si maa lepa fun ju ohunkohun lọ niwọn igba ti a ba jẹ ti Rẹ̀. Adura wa nigba gbogbo ni lati jẹ “Bi oju rẹ kò ba bá wa lọ, máṣe mú wa gòke lati ihin lọ.”

**A Kún Ọkàn ti Ebi Ẹmi N Pa**

Mose ko ni itẹlọrun sibẹ. O fẹ lati ni ẹkun rẹrẹ ohun ti ọmọ eniyan le ri gbà lọwọ Ọlọrun ni ayé yii. O n fẹ ifarahàn Ọlọrun ni kikun lati ọdọ Ọlọrun, ju eyi ti ẹnikẹni ti ní rí lọ. Oun kò ṣafẹri ohun igba diẹ tabi ògo asán ayé yii. O n fẹ iṣipaya Ọlọrun ti o logo, ni kikun ju eyi ti o ti ri gbà nibi ti igbẹ ti n jó – o n fẹ sun mọ Ọn si i ju igba ajonirun ina ori oke ni lọ, o si n fẹ tẹ́ ọkàn rẹ̀ lọrun ju ti igba okunkun biribiri lọ tabi ọwọ̀n awọsanma ṣiṣu dùdù. Gbogbo ifẹ ọkàn rẹ̀ ni lati ri ogo Ọlọrun. Oluwa fi ibeere rẹ fun un ni rirọra fi aanu fesi nipa mimu ki Mose mọ

gbogbo oore Rẹ̀. O fi inu rere Rẹ̀ hàn fun Mose dipo ogo Rẹ̀ lai ni iboju, ati nipa kikede orukọ Oluwa niwaju eniyan Ọlọrun yii.

Ninu ẹkọ wa niwaju a o tubọ ri i bi Ọlọrun ti dán Mose wò lọna gbogbo ninu awọn iṣẹlẹ wọnyii. A o ri i bi Mose ti fi hàn pe oun jẹ ẹni ti a le fọkan tán pẹlu ẹrù nla ipo alakoso yii ati bi a ti dán ifẹ ọkàn ati yíyẹ rẹ̀ lati jẹ alagbawi fun Israẹli wò nihin yii. A o ri bi o ti ṣe aṣeyọri ninu gbogbo wọn, ti o si fi han pe ki i ṣe ogo asan ayé tabi okiki ni oun n fẹ bi ko ṣe agbara Ọlọrun ati ibukun Rẹ̀ lori ayé rẹ̀ nigba gbogbo.

Wò ó bi o ti dara to fun Mose lati duro nibi iho apata ki o si mọ pe ọwọ́ Ọlọrun daabo bo oun kuro lọwọ ina ajonirun ti ifarahan Olodumare! Wò o bi ayọ̀ rẹ̀ yoo ti kun to lati ri ohun ti oju ẹda kan ko ri ri, ati lati gbọ́ ohùn Oluwa ti n kede orukọ Oluwa, Jehofa, pẹlu awọn ẹwa iwa Rẹ̀ ti inu rere, oore-ọfẹ, ati aanu!

Wo ipo giga ti Mose oloootọ eniyan Ọlọrun yii de laaarin awọn ogunlọgọ ọmọ-ogun Ọlọrun! O ri bẹẹ fun un nitori o ka oju rere Ọlọrun si ohun iyebiye ju ohunkohun lọ ninu ayé yii. Awa paapaa le de ibi giga ti Ọlọrun pese silẹ bi a ba "tète kọ́ wa ijọba Ọlọrun na" nitori a ti ṣeleri pe "ọwọ Ọlọrun wa mbẹ lara awọn ti nṣe afẹri rẹ̀ fun rere" ati pe "kò si ohun rere ti yio fà sẹhin lọwọ awọn ti nrìn dede."

**AWỌN IBEERE**

1. Ni awọn akoko wo ni Ọlọrun ṣeleri fun Abrahamu ati Jakọbu pe a o fi ilẹ Kenaani fun iru ọmọ wọn?
2. Ki ni iyipada ti o wà ninu eto Ọlọrun fun awọn Ọmọ Israẹli nigba ti Ọlọrun sọ pe Oun yoo rán angẹli kan ṣiwaju wọn?
3. Ki ni iha ti awọn Ọmọ Israẹli kọ si ọrọ ti Ọlọrun sọ lati ẹnu Mose?
4. Nibo ni Agọ Ajọ ti wà tẹlẹ, nibo ni Mose si gbé e lọ?
5. Ẹkọ nla wo ni a ri kọ́ nipa lilọ ti awọn Ọmọ Israẹli n lọ si ibi Agọ?
6. Ki ni awọn Ọmọ Israẹli ṣe nigba ti ọwọ̀n awọsanma sọkalẹ sori Agọ Ajọ?
7. Bawo ni Bibeli ti ṣe ṣapejuwe irẹpọ ti o wà laaarin Mose ati Ọlọrun?
8. Ki ni ibeere ti Mose kọ́ beere lọwọ Ọlọrun ṣaaju ki o to wi pe oun fẹ ri ogo Ọlọrun? Eredi ibeere naa?
9. Njẹ Ọlọrun gbà fun un bi? Njẹ a le beere ohun bẹẹ nigba ti a ba n gbadura?
10. Ki ni ṣe ti Ọlọrun kò gba fun Mose niti ibeere rẹ lati ri ogo Rẹ̀? Ki ni Ọlọrun ṣe dipo eyi?